# EKO AKETE.

"Emi yio fi ohun ti o ndun Makunnu han awon Alagbara, Ngo si je Alagbawi awon Odi."—W. T. Stead.

Vol. II. No. 71. SATURDAY, NOV. 17, 1923. Fourpence.


## DURO THOMAS.

55, MASSEY STREET, LAGOS, (NIGERIA.)

P.O. Box 374. Telephone No. 243.

*The Best House for every Description of German Goods.*

**"Specialities: Enamelware, Beer, Wine, Iron Bedsteads, Ruby Plates, Rubber Beads of all kinds, Clay and Briar Pipes, Champagne, Cement, Biscuits in cases, Gun Powder, Wire Nails Raugoon and original Ballam Rice, Accordeons, Piano, Padlocks, Beads, etc., etc., etc."**

Ọgbẹni **DURO THOMAS**

Onișowo-towolawi, ni awọn IBUSUN mèrémèré onidẹ to ṣẹṣẹ de fun u lati ilu Jamani wa fun tita ni Ile Ọja rẹ 55, Ita Măse leti ita Faji, l'Eko.

## N. V. HANDLEMATTSCHAPPIJ V.H.

### J. F. SICK ati AWỌN ẸGBẸ.

No. 7, Ita Ibode lailai, l'eti *Glover Memorial Hall, (Customs Street,)* EKO.







Awọn Oyinbo Onișowo yi nranșẹ MASINI-ARANSO ti a npe ni VESTA Nos. 1–4 t' ọlwọ ati t' ẹlẹsẹ ni owo to rọju, a le fi iye-owo wọn han ẹnikẹni to ba lọ si Ile-owo yi.

Nwọn mura tan lati ṣe adehun pataki pẹlu ẹnikẹni to ba fẹ ranșẹ Mejila tabi jubẹ lọ ninu MASINI na.

...yinbo yi nșe orișirisi Ilẹkẹ alarabara, nwọn si nranșẹ *Cement* ati panu kikọle to nipọn, ati ẹja abọmafọ ati orișirisi ọja.

Ilẹkun Ile awọn Oyinbo yi și nigbakugba ti enia ba fẹ lati lọ ba wọn sọrọ ASIRI nipa OWO. IROHIN KO TO AFOJUBA.

**J. C. VAUGHAN**

Ti Ile-Ọja Sheffield ni Ita Kakawa ati Ile-Ọja "*Excelsior*" ni Ita Agarawu, ni oniruru awọn ohun sikọle fun tita ni owo ọpọku-ọyọku.

O ti nṣowo Irin Iṣẹ lorisirisi lati adọta ọdun sẹhin titi di oni.

ATARI AJANAKU ni ỌGBẸNI na jẹ ninu awọn onisowo Irin Iṣẹ ni ilu Nigeria.

ỌKỌ tita wa ni owo pọ ọ.

---

**B. O. Joseph**

*Commission Agent.*

21 years experience in trade.

**Cotton.**

**Sundries.**

**Hardware.**

**Provisions.**

27, Koseh Street, Lagos.

---

**...e British Psychological Institute**

OF BOLTON, ENGLAND.

...ches by Correspondence the following ...iences :—Psychology, Philosophy, Phrenology, etc., etc.

For complete particulars, apply to the Official Representative of the Institute for Nigeria and Gold Coast Colonies

C. GLADSTONE-MACAULAY,
P.O. Box 384,
Lagos.

*Youngmen, for future's sake, be on the alert.*

**THE LAGOS HO...**

Iced Drinks of every description on sale at the above popular Hotel.

Clients' comfort occupies a prominent part in the programme of the establishment.

Billiards playing forming a centre of attraction.

**TERMS :—Strictly Cash.**

H. H. KING,
*Proprietor.*

Portonovo Market St.,
Lagos.

---

ILE ERO TI EKO.

Ohun mimu Olomi didi to np'ongbẹ enia nbẹ nihin lorisirisi fun tita.

Ko si ọna ti a ko ngba fi tẹ awọn onibara wa lọrun.

*Billiards* idaraya si wa fun ẹnikẹni lati fi sere. Owo-lọwọ la fẹ.

H. H. KING,
*Oni-nkan.*

Ita Ọja Ajaṣẹ, Eko.

*Editor & Proprietor:—*
ADEOYE DENIGA,
*Office:* 24, Williams Street,
P.O. Box 286,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILE NI OWO GBIGBA RE.

| Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|
| Ọdun kan 12/- | 13/- | 14/- |
| Oşu mẹfa 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oşu mẹta 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranşẹ si *Editor*.

## GBOHUN-GBOHUN.

—:o:—

### ỌSỌ OLOWO IGANDO NKẸ-RIRI LỌGBA ẸWON.

Şamuşamu ni ọkọnrin kan ti o njẹ Ọsọ ni Abẹokuta njẹnu nigbati Adajọ ibẹ ju u sẹwọn ọdun meje ati ọdun mẹta pẹlu işẹ aşegan, nigbati a mu u mọ owo şile aiyederu ti o ti nşe, on ati obinrin kan ti o njẹ Mọlojo ni a ra mu fun ẹşẹ yi, şugbọn ori yọ iyẹn nitoriti o bọ; ọkọnrin yi nikan lo f'ara korin gbogo o ẹşẹ na; ọdun meje pere nikan ni yio fi şe işẹ asinbori f'ọba fun iwa aşemaşe rẹ yi; ofin amunimuye (*Criminal Code*) lo gbe ọdẹlẹsinrin na la.

### ỌMỌ ALUFA, Ẹ KU EWU OJO!

Ni iwọn agogo mẹwa arọ *Sunday* tokọja, Ọkọnrin kan ti o npe ara rẹ ni David Saka lọ sile Ọgbẹni William George ti o nşişẹ ni ile owo nla (*B. B. W. A.*) ni 'le rẹ ni 26, Ita Ẹlẹgbata, o si le awọn ọmọde to ba nile si ta, o ni on bere Ọgbẹni George baba wọn, nigbati a si sọ fun u pe ko si ni 'le, bẹni o joko; tohun-tẹnu Mrs. Ọgbẹni na de lati *Church*, lọgan, alakọri yi si ra giri mọ iya afin na, o si vọ ọ bẹ si i; o di ogun "Ẹ gba mi o! Ẹ gba mi o!!" eyin a wi yi pẹ, bẹni masondoki ọkunrin yi rọ wọ ile, o si ko gbogbo kọkọrọ yara to ri awọn aladugbo si rọ wo ile lati wa dabobo Mrs. George, nwọn sile ọkọnrin na si'ta; a gbọ pe bẹ lo f'ori le ile Ọgbẹni S. H. Pearse Ọ'ọla o si ba Ọgbẹni Tychus Aganga Williams ni'le, gẹgẹ bi oju ọkọnrin yi ti ranko, bẹni Ọgbẹni Williams yara yẹra fun u; nigbati Ọgbẹni George si de ile, ti a rohin agbako yi fun u, lọgan o dorikọ şibu Ọlọpa ni Ita Tinubu lati lọ sọ ti jamba na fun nwọn; a si dupọ pe nwọn ra ọkọnrin alakọri na mu o si wa ninu itimọle nisinsinyi a si gbọ pe awọn Dr. ni boya ori rẹ ni ko-pe, nwọn nbojuto lọwọ. A sọ pe ọlọpa kankan ki nşọ apa ibi Ẹlẹgbata yi, bi eyi ba ri bẹ, a ke si awọn Ọgbẹni T. I. Kester, R. B. Re[illegible] Amos Ọpẹnibo ki nwọn maşi şe [illegible] ati ma jẹ ki ọlọpa ma şọ ibiyi.

Bẹ si ni a gbọ pe awọn olé ni Ẹlẹgba[illegible] ko Mrs. Ọgbẹni Henry St. James l'ọja oni pọun mẹrinlẹladọrun (£94) ti o gba lọwọ awọn Oyinbo onişowo Ollivant l'ọsẹ to kọja.

D

### ABỌ O, AFORIN IŞẸ OLUWA.

Ọgbẹni T. K. E. Phillips bọ wa sile lati Ebute Mẹta, nibiti o ti lọ gbatẹgun lẹnu oşu mẹrin sẹhin. Abọ o!

### EGUN NLA TI NFỌHUN BI ENIA.

> Adaba nf'ogede, o şe b'ẹiyẹle o gbọ, Ẹiy[illegible] gbọ, ntiri lo ntiri,
>
> Ajaku ẹwọn lo nkọ Aparo lọgbọn, ara ile [illegible] ni nkọ ni loro.

Irufẹ ọrọ yi lo jade l'ẹnu wa, nig[illegible] a ka Wasi ti Ẹni-ọwọ Alabejuto S. Coker ti oke Olowogbowo l'Eko [illegible] şe nigbati Ijọ *Bethel* şe ayajọ ọdun ko[illegible] lelogun ti nwọn ti bọ "loko ẹru" l'ọ[illegible] kọja nipa dida *Church* Ọmọ-ibi[illegible] Iwe Iwasu na wa fun tita lọdọ S[illegible] Ijọ na Ọgbẹni "*Major*" O. Ad[illegible] ti No. 77 ati 79 ni Opopo-nla; [illegible] nta ni ọdọ Ọgbẹni Adenmji Ol[illegible] Ebute Mẹta; sisi (6d.) pere ni. [illegible] ati Ẹkọ inu rẹ ju iye owo yi lọ[illegible] ani. A ba awọn Ijọ yi yọ, a si [illegible] Igi-iwe yi fun Wāsi na.

## ẸNI KO KE'WE Ẹ KU IYA.

### AWA NNAWO "GEGE."

A ba Ijọ ọmọ Ibilẹ *( U N.A.)* ti Eko yọ fun pipari ti nwọn pari Ile-iwe titun ti nwọn bẹrẹ kikọ rẹ fun awọn ọmọ Ile-iwe wọn ni iwọn ọsu diẹ sẹhin.

Nigbati a kọsẹ wọ inu rẹ ni lọlọyi Alufa Alabojuto G. A. Oke ti a ba nilẹ-nigbana si mu wa rin gbogbo ile na jakejado; atẹgun ibẹ tu ni lara o si dani loju pe lẹhin igbati a ba ti si i tan gaṣa ni ọmọ ti ao kọ nibẹ ti yio jẹ ab'oridọta. A ba ...i Ogunrombi ọga Ile-iwe ibẹ yọ fun ... ni nipa Ile-iwe titun ti awọn Ijọ ... kikọ rẹ lakoko rẹ.

## OGI PARADA, O D'ẸKỌ !!!

Bẹ si ni a ba awọn Ijọ Ọmọ Ibilẹ (*Bethel*) yọ fun yiyọri ti Ile-isin ti nwọn ...ọ ni Opopo-nla nyọri bọ nisinsinyi; ...un kẹwa (1913) ti nwọn ti wa lẹnu ...ẹ niyi, ni ọdun kẹjọ ọhun (1915) ni jamba nlá-nlà yẹn ṣe *Church* na, nipa didawo ti apakan rẹ dawo l'ọsan gangan ni iwọn agogo mọkanla kọja, idamu ati ẹrujẹjẹ to ba gbo bo *Member Church* na, papa ... Ọgbẹni pataki-pataki ninu Ijọ na, ... bi Ọgbeni A. W. Thomas baba ...ẹ *Church* na lakoko yi, Dada ...lesigbin, James A. Sulr, A. W. Allen, ...ev. Oguntolu, N. T. O. Davies, Akibọ ...iyaolu, ọga iṣẹ na (to ti di Ologbe) ati ...wọn miran. A si gbọ iyọṣutisi ti awọn ...a nyọ si nwọn pe "Họwu!" kini ohun ... Ẹ fẹ kọ Ile Iṣọ Babel ni?" Ati Officiondoki ọrọ bawọnni; bẹ na ha kọ ni ...irohin kan ọmọ-da-iya'ẹ-loju fi igba da Ijọba ninmọran pe ki nwọn da iṣẹ ...ọ na duro bi? Ko si ẹnu ẹniti ko ...nigbana; fun iwọn ọdun mẹta a ko ...bẹni a ko gbọ mu, ni biba iṣẹ na ...wọn elomiran tilẹ ndapara pe ki ...ember *Church* na ta fun awọn *Youngmen*, awọn ọta aje odi okan, bi ẹnipe ...n lo gbe aje ṣọnlẹ ti o fi yọ ...i a dupẹ pe iṣẹ *Church* na nlọ ...d nisinsinyi; tobẹ ti a ba wọ ...i wo o, ko s'orukọ meji to yẹ ju AWOYIRUN ILE OLUWA lọ. A ki awọn ọga iṣẹ to wa nibẹ nisinsinyi, awọn Ọgbẹni Derby, J. 'Bagan Benjamin, C.E., ati N. T. O. Davies ku'ṣẹ. Fi-ọgbọn fi-ọgbọn *Church* na ko lẹgbẹ, ki Baba da gbogbo wa si t'ọrẹ t'ọta, fun igba ṣiṣi rẹ; ọwọ a ran iyoku o. Aṣẹ !!!

## AYỌ ABARA TIN-NTIN.

A ba Ọgbẹni Theodore Williams ti No. 7 Ita Taiwo yọ fun bibọ ti o bọ ni *Wednesday* ọsẹ yi ninu ẹjọ ẹwọn ti awọn Oyinbo Ajeji (*French Company*) nba ro ni Kotu awọn ọlọpa lẹnu ọsẹ mẹrin to kọja.

## ARA LILE NIPẸKUN ỌRỌ.

A ṣe Ipade ọsẹ Ilera ni Ile Afari Ogun ni ọjọ Alaruba (*Wednesday*) Ọsẹ yi Dr. Foy ni Alaga Ipade na.

Diẹ ninu awọn to sọrọ ni iwọnyi :—

Dr. Clark, Ọgbẹni L. A. Cardoso, Dr. O. Ṣapara I.S.O. ati awọn jakanjakan miran.

Awọn ti o joko ti Alaga laika awọn to sọrọ ni :—

Ven. T. A. J. Ogunbiyi, Peter J. C. Thomas, G. Debayọ Agbebi, Mrs. A. Gibson, Miss Ọrẹ Greene ati Iya-afin kan ti a ko mọ orukọ rẹ.

## ẸBỌRA WỌ'LU, Ẹ GBARADI.

Lieut-Col F. H. Hammond ẹniti Ijọba Gẹsi yan lati wa wadi iṣẹ ọko-i'ẹ *Nigeria* ba ọkọ *Adda* de ni Alamisi *Thusday* ọsẹ yi.

Diẹ ninu awọn onipo ninu Iṣẹ Ọba si lọ pade rẹ.

## RIRO NI T'ENIA, ṢIṢE NI T'OLUWA.

Gbukẹ la gbọ pe wiwa Igbakeji ọga awọn Gomina Ọgbẹni Ormsby-Gore, Ọlọla M.P. yọ fun igba diẹ.

## Ẹ KU AGBA, AGBA KU IYỌNU.

A ba Ọgbẹni wa Mr. A. E. Carrena, Akọwe agba ti ile wọnlẹ-wọnlẹ (*Chief Clerk, Survey Department*) yọ nitoriti o di

ẹni adọta ọdun ni ọjọ Alamisi ọsu yi ( 15th *November* ) ni ọjọ kan na o di ọdun mẹdọgbọn to ti gbe arẹwa rẹ Obinrin Mrs. Agnes Carrena ni iyawo. Awọn ọmọ rẹ ( *the Young Carrenas* ) fẹ ṣe bẹbẹ ni oni lati ṣe iranti ava ọjọ na Ki Baba ma ṣai fi ọpọlọpọ ọdun han wọn, ko dẹ fun awọn obi wọn ni ẹmi lati sin wọn de ibiti ẹru ko ni ba wọn, ati pe ki ọmọ le ṣe bẹ fun awọn na pẹlu. Ire a kari o.

VINTURA, O KU'RỌJU.

A ba Ọgbẹni Shaffi Vintura ti No. 49 Ita Glover, Aṣoju awọn Oyinbo C. F. Hutchinson nibi, daro iku obinrin rẹ kan to ṣẹlẹ ni'le Ọgbẹni na ni Alamisi ọsẹ yi.

AGBỌJỌKU ỌRUN RERE!

Anu ṣe ni lati gbọ ti iku Ylonfun Agbọjọku iyekan Oloye Jẹngẹn ni Agbadarigi. Ki Ọlọrun ko dẹlẹ fun u. Ijọ Ọmọ Ibilẹ ki ọ Oloye " Mi ku ọvọ, Mi ku asẹhinde "

O ṢEUN! ỌMỌ ONISARO ỌWẸNGA.

Inu wa dun lati gbọ wipe ọrẹ wa Lawyer H. Withnell Williams npete lati kọ ile nla kan si Ebute Agbadarigi; bi ẹlẹgiri ti san ṣokoto bẹni aya rẹ di ọja. Eyi wun wa o!

---

### DISTRIBUTION OF CERTIFICATES WON BY CHORISTERS OF CHRIST CHURCH PRO-CATHEDRAL BY MRS. H. CARR

Characteristic of Christ Church functions, a very enjoyable and decent social gathering was had on Saturday last, the 3rd instant when certificates won by some of the choristers of Christ Church Pro-Cathedral at the last local examination of the Trinity College of Music were distributed.

After partaking of the sumptuous refreshment provided speeches were given by :—Mr. T. K. E. Phillips *( Organist & Choir Master )*, Mr. M. A. Akinsemoyin *( Patron of the Choir Club )*, Dr. O. Obasa, Mr. G. D. Agbebi and Mr. H. Carr *( Chairman )*. The certificates were distributed to the successful boys by Mrs. H. Carr as follows :—

*Preparatory Grade :*

ADENIYI SAPARA — MODUPE WILLIAMS
E. BENKA COKER — NATHANIEL B. AGBEBI
MICHAEL O. COLE.

Certificates awaiting distribution.

*Intermediate Division. June 1922.*
MOSES O. CRAIG

*December 1922.*
N. S. DEDEKE

*June 1921.*
D. ASHLEY

*Junior Division, December 1919.*
O. O. TAYLOR

*Associate of Music Grade, July 1920.*
T. K. E. PHILLIPS.

This latter record is a proof of the ardour o[f] Phillips to lead the way and give encouragemen[t] others; has to be remembered that it was only other day here that he passed his Inter. Mus. It is hardly necessary to repeat there is a great adva[ntage] attached to the study of both the theory and pr[actice] of music in a methodical manner. Thanks to M[r.] O. Obasa, Mrs. M. A Akinsemoyin, Mrs. E. A. and other young ladies for the suc[cess]

All concerned are congrat[ulated]

6/11/23.

---

## Open Letters.

TO CELEBRITIES, NOTORIETIES, ETC., IN D[IFFERENT] WALKS OF LIFE.

**No. 40.**

To

THE HONOURABLE
C. W. LEESE,
*Acting Treasurer,*
The Treasury, Lagos, Nigeria.

My Dear Croesus,

Complaints reach me of the refusal by th[e] accept old English silver coins with the Queen's [h] uncrowned! and coppers bearing both Queen and King Edward VII's effigy when tendered for

This point-blank refusal, to a lay mind is in particularly as the coins are genuine legal te[nder] circulation has NEVER as far as I know been [] any Order-in-Council. On the contrary, I re[] even the Local Government once announced [] posters, their being readily accepted for pa[] tendered in any of our public Offices: w[] *Polloi*, especially, our market women have studied aversion to the Specie of this ty[] holler: would it mean that an average [] owns some of the metallic currency w[] from purchasing the wherewithal of li[] ing it on the sole ground that she i[] to possess it? This seems a [] is growing the horse is starving!!!

Now then, in the interest of those i[] you will be doing a mighty good to [] coming to their rescue in causing a b[] about town insisting on the acceptanc[e] for value received on pains of penalty

By this, you will be relieving man[y] Poor, of the difficulty in which they [] for owning a legal tender which [] to receive for payment, (though s[] through no fault of their own.

Two to one, your winning smiles wi[]

# EKO AKETE.

EKO, SATURDAY, NOVEMBER 17, 1923.

## EWO LEWO, ẸNYIN ỌMỌ LẸHIN ONIṢẸ NLA?

## KO HA SI OLORI L'AGANYIN NI BI?

Niterigbaṣo Lemọmu Brimah ninu oṣu ...ber tokọja, ṣi aye Ipo Oye na si ẹ fun lẹhin igbati o ti jẹ ẹ: nipa eyi awọn ti ao kọ ni pataki ninu Isin na bi Sẹriki ...ni, Baba Adini, ati awọn onipo ...ẹlu ọgọrọ awọn Janma, si fi Alufa Nọla ti Oko-awo joye Lemọmu-Eko ni *Sunday* tokọja pẹlu ẹyẹ nla ...alaṣi nla ti Ita Victoria. A gbọ pe ...to wa sibi oye yi le ni ẹgbāta enia (6000) l'ọkunrin, l'obinrin. Ikun-diẹ wa larin apakan awọn Imale keji; a si gbọ ti nwọn sọ nipe Alufa Tijani ...i Igbakeji Lemọmu Braimah Ologbe ...o na tọ si; eredi ti nwọn wi nipe, o ti ...i ipo Naibi na fun Lemọmu Braimah ...wọn ọdun mẹrinlelọgbọn; esi ti a gbọ ...n Janma fi si eyi ni pe:—

Otọ ni Naibi na ti wa nipo yi fun ...ọ ...dun, ṣugbọn mimọ Keu rẹ ko ... fun u lati fi si ipo Aṣoju gbogbo ...bi Lemọmu-Agba. (2) O ni iye ...Naibi na ko le ke Kutuba (*Khutba*) ...n nigbati o ba nṣe Isin niwaju ...ma. (3) Oye Naibi ko tọ suna, ...o si aṣẹ fun u ninu Alkoran. ...si wà fun eredi yi ninu awọn ...ilu nibi pọ rekọja àlà: ẹ jẹki a ...lẹsẹsẹ, ka mu Ekinni ati ...

Ipo Lemọmu-Agba ki nṣe ...ni tiwa ẹniti o le ke Rafa-nda ...ò si ja fáfá ninu rẹ lo tọ, lo si ...i a fi si iru ipo to larinrin bẹ; ... ba si yan ẹniti nwọn mọ ni ... pe ina oye keu rẹ njo ...ko rope nwọn ṣi yan; pāpā ...bẹ ba jẹ ifẹ inu ọpọlọpọ ninu ... ni ti ọna Oyinbo, bi ọgọrọ enia ba wa fun imọran kan ti ẹnikan ba mu wa si Ipade kan, ohun ti ọgọrọ enia na ba wi, ni yio jẹ aṣẹ, tabi gẹgẹbi a ti nwi lede Gẹsi bayi *Majority carries the Vote* eyini ni ọgọrọ enia lo wa fun kinni yi; ẹnyin ẹ wo asẹhinwa asẹhinbọ didibo fun awọn mẹwa ti nwọn fẹ lọ ṣoju Ilu ni Ajọ Igbimọ Aṣofin ti a ṣe ni lọlọyi, ẹ o ri pe jātanyo ẹṣin ni awọn meje toku ti "Ifa nwọn fọ ibi" gun lọjọ na nigbati Ibo ko mu wọn. Ifẹ ọpọ enia ko ṣe rọ̀ti sapakan bọ̀rọ̀.

(3) Bi ipo Naibi wa ninu Alkoran ni o, tabi kosi, jẹ ohun ti ko to fun'ka mọ tobẹ nitoriti a ro pe awọn enia iba ti sọ eyi telẹ lọjọ gbọ̄rọ nigbati a fẹ fi Alufa Tijani na sipo yi nigbāni.

Ni ọjọ Alaruba ọsẹ yi ni dẽdẽ agogo mẹjọ-abọ ārọ, awọn apakeji Musulumi ni ārin wa nibi tun fi Alufa Tairu Naibi na jẹ Lemọmu Agba ti Eko; a gbọ pe "iṣetutu" oye na ni Mọṣalaṣi kanna, ko ju iwọn abọ wakati lọ; Loju wa, eyi jẹ ohun tó wọ́, eyiti Oyinbo npe ni *irregular procedure* ọna to lọdi ikoto, to si lodi patapata ni.

Kiloṣe ti awọn enia wa kole tẹle imọran tabi àbá ọpọ enia gẹgẹbi a ti la a silẹ ninu Iwe yi?

Kiloṣe ti ọlọgajọga ati olohunyọhun pọ bẹ larin awọn miran to npe ara wọn ni agba?

Kiloṣe ti awọn ẹlomiran fẹran idarudapọ ju eto ati igunrẹgi nkan lọ?

Ko ha to asiko ki a tilẹ sinmi ninu oni Ija ọla Asọ?

Ti oju ko ba ti ole, o yẹ ki oju ti onihun.

A fẹ ki awọn oniṣẹ ijẹrin mọ pe nipa dida nkan miran silẹ bayi, O di Adiẹ ba lokun ara ko r'okun ara ko r'Adiẹ, bẹ ẹniti o ba pa Inaki, lo ma gbe Inaki pọn.

Nijọ melo la o ṣeyi gba? A bẹ awọn ara wa wọnyi ki nwọn maṣai dakun siso irun iwaju pọ mọ ti ipakọ bayi ki araiye ma ba sọ wọn lorukọ bi ti Ọkọnrin kan ti o ni on njẹ Aru-bọ-ki-ija-o-ṣẹ! Ẹnyin Musulumi na ni ẹ ma nsọ pe ọrọ Ọlọrun ko mu ija wa; eyi ko ha mu kumọ ati ọgọ dani baun?

Agbalagba d'ọwọ nyin o!

## WOSIKA.

[ *Lati ọwọ* ATARI AJANAKU. ]

Lati igbati Lemọmu Buraimọ ti ku, ni a ti nṣe aṣaro ẹniti yio ropo rẹ, mo si tanmọ pe gbogbo ẹniti o nka "Eko-Akete" ni yio ranti Wosika ti mo ṣe sinu rẹ l'ọsẹ kẹta ọhun, Oktoba 27.

Ni *Sunday* ọsẹ to koja ogunlọgọ enia lo lọ si Mọṣalaṣi Jimọ lati wo ẹniti a o fi jẹ Lemọmu, ile kun, ọna bo, ẹse gbogbo Alhaji ilẹ yi lo si fẹrẹ pe tan sibẹ. Lawani npe Lawani ranṣẹ, Afa Adamu Anlmaṣaun lo koko sọrọ, lẹhinna Seriki Musulumi, lẹhinna Baba Adini gbadura, lẹhinna ni lemọmu Abasi olori awọn Ratibi sọ fun janmaa pe orukọ enia marun ni awọn ti rọ, siwa-sẹhin lati fi ọkan ninu won jẹ Lemọmu. Alhaji Alli Fahm, Alhaji Isa Shitta, Alhaji Salisu, Afa Tijani Iaibi ati Afa Ligali Nọla.

Lai-fa-gun-lọ-titi, o ni Afa Ligali olohun iyọ ni ibo wọn mu gbogbo janma si ho iho ayọ lati gbọ bẹ, lẹhinna ni a wa gbe Agbada Sanyan nla wọ olorire yi. Afa Abudulai olori ọmọ kewu si we Lawani fun. Titi a fi ṣe gbogbo isin yi tan ko si ija, ko si'ta, awọn Ọlọpa si fi fere dabira ni'jọ na ni Ita Akọni.

Gbogbo oye to mbẹ lode aiye, ibaṣe Biṣọpu ti awọn omouku, Lemọmu ti Imale, Baba oloriṣa ti Aboriṣa, ipo giga nibi iṣẹ tabi oye Aṣe'lu titi de oye Ọba l'ori itẹ, gbogbo wọn patapata lo ni ijakadi larin olukuluku ẹniti o tọ si, ti nwọn si ndu lati jẹ ẹ.

Kabiyesi! Njẹ Ọni Alaiyeluwa to joba Ile Ifẹ nisisiyi, Alafin to wa lode Ọyọ, Ọwa ti Ileṣa, Oṣemọwe ti Ode Ondo, Alake ti Abẹokuta ati awọn Ọba Alade wa miran le wipe ẹnikẹni ko ba wọn du Ade ti o wa lori wọn nisisiyi ki Ọlọrun pipa to gbe de wọn lori; tabi Gomina Eko, ti Saro, ti ilu Aganyin ati Gambe lo ma wipe ẹnikẹni ko ba wọn du ipo ọla ti ọwọ wọn tẹ nisisiyi. Ẹ bere lọwọ Aṣidikini Ogunbiyi ti ṣọṣi *Breadfruit*, Alufa Victor Johnson ti Araloya, Alufa Gansallo ti Ebute Ero bi wọn ko ba ni alatako ri, ẹ gbagbe pe ọtọtọ enia mẹwa lo ndu ipo Aṣọju Eko mẹta pere ni Igbimọ Aṣe'lu nijọsi, tabi ẹ ro pe bi a ti yan Ọgbẹni S. H. Pearse, baba Ayọ, fun Aṣ'oju Ẹgba dun mọ lagbaja ati tamẹdu ninu? Bi a ba le ba enia du oye wọnyi ikelo ti oye Lemọmu.

Tani nkan rere ko wun? Ko ha wun iwọ ti o nka wosika mi yi ko lọgbọn ju Herbert Macauley lo, ko mọ'we ju Henry Carr, ko ni'le pupọ ju Alli Balogun, ko mọ "Saikọloji" (*Psychology*) ju Tommy Jackson, ko gbọ rafanda oyinbo ju Shyngle, ko lowo ju Josiah Doherty, ki iyawo rẹ bi ibeji ju aya Loya Taylor, ko mọ orin kọ ju Biṣi ati Ijalẹ, ko ni asiki ju Dokita Sapara, ko ni ola ati iyi ju Bihop Oluwole, ko ni ibalẹ ọkan ju awọn ọmọ Payapaya Candido ati Dokita Rocha, ki oko *cocoa* ati obi rẹ ju ti J. K. Coker, ki Loya ati Surveyor to wa ninu ẹbi rẹ ju ti awọn Agbebi lọ? Ṣugbọn nibo lo fi kadara si—ki Ọlọrun pin ire fun gbogbo wa o.

Alufa Ligali ti awọn Ratibi ati ilu fi jẹ Lemọmu gẹgẹ bi ofin ati ilana ẹsin nian takadi, ko ṣẹhin Ọlọrun—Ọlọrun lo fẹ bẹ ẹ. Nitorina a bẹ gbogbo Imale Eko l' okonrin, l' obinrin ki nwọn fi ye de 'nu ki nwọn si juba fun Afa Ligali bi Lemọmu. Ki nṣe nitori temi, ki nṣe nitori Seriki Musulumi, ki nṣe nitori awọn Ratibi, ki nṣe nitori gbogbo Janma, bikoṣe nitori alafia ilu ati nitori Anabi onisẹ nla. Bi o ti wu Oluwa lo nṣiṣẹ, nigbamiran a fi baba silẹ a da ọmọ l' ọla, a fi ẹgbọn silẹ a fun aburo ni asiki—ẹ ranti anabi Musa pẹlu Aruna ẹgbọn rẹ, awọn mejeji lo sa "Kewu" ja.

### A NSỌRỌ ATATA EKO NSỌ MARO!

Ẹniti o nsọrọ to si nro nipa nkan to nsọ ni mo pe "Eyiowuawu" ọmọ "Eleti Ọfẹ," nko mọ pe ẹniti ko roye rara ni; ṣugbọn o ṣe nkan to dun mọ mi ninu "Eleti Ọfẹ" ti ijẹrin nigbati o wipe ọrọ ti mo ba on wijọ si, on ti gbe e danu. Anu si ṣe mi pe imi to ni on tun gbe de, ọrọ ko si ninu rẹ. O dabi igbati nwọn npe enia l' ole to si ngbe ọmọ ẹran jo. Eyiti oniwe irohin "Eleti Ọfẹ" pipa sọ pe awọn oyinbo nsinku si Westminster Abbey, apo ara rẹ lo sọ si, ko ba ọrọ to wa nilẹ mu. Iyoku iregbe ni.

Lẹkan si, a tun bẹ awọn oniṣokoto gbọrọ ati Ijọba ki nwọn maṣe da sọrọ ẹsin Imale, ṣugbọn ki Ijọba jọwọ sa gbogbo ipa rẹ fun ire ati alafia ilu, nwọn si le da sẹria fun ẹnikẹni iba ṣe Imale, Aboriṣa tabi Onigbagbọ to ba fi ara rẹ joye "arijẹ ninu ọtẹ ilu."

Ẹnyin Onifila funfun, ẹnyin Aṣoju Eko, ati Agbagba lọtun losi, agba dọwọ nyin o!

Emi ni ti nyin nitotọ,

ATARI AJANAKU.

---

## Stop Press.

### MR. ORMSBY-GORE'S PROPOSED VISIT DEFERRED.

*Reuter's* learns that the proposed visit to West Africa of Mr. Ormsby-Gore, M.P., Permanent Under-Secretary of States for the Colonies has been deferred for the noncé.

[ ED—EKO AKETE.]

"*Ke rara ma si şe dasi, gbe ohun rę soke bi ipe, ki o si fi irekoja awọn enia mi han wọn ati ile Jakọbu, ęşę wọn*" Isaiah 58, ęsę 1;

Ọrọ oke iwe yi, ni emi Samuel Woli Kekere yio fi bẹrẹ iwe mi, si oniwe "Eleti ọfẹ" ati "Eko Akete;" ati awọn meje ti emi Samuel Woli Kekere daruko ninu iwe yi ni ọsẹ to kọja.

Emi Samuel Woli Kekere si fe ki olukuluku ki o mọ daju daju pe, "Samuel Woli Kekere" ko jade lati "dasi," şugbon lati "ke rara," kişe lati "dajo," şugbọn lati fi "irekoja han."

Samuel Woli Kekere ko jade lati şe ojesaju ẹnikẹni, şugbọn lati fi irekọja olukuluku han, ibaşe ni işę rere rę, abi buburu.

Ọrọ yi, "ke rara ma si şe dasi," ni emi Woli Kekere ri li oju iran l'ori akete mi li oru, nigbati mo si taji li oju orun mi, mo ri pe iran ni; ọkan emi Samuel Woli Kekere ko si ro ohun meji, bikoşe ti ẹnyin alagba, Baba nipa ti Ọlọrun; ẹnyin ti ire ati atidara Ilu ati awa ọmọ nyin mbę lọwọ rę l'oni, adura emi Samuel Woli Kekere ati ero ọkan mi ni pe, ki Ọbangiji Ọba ogo ki o ran nyin lọwo.

Şugbọn nigbati emi Woli Kekere tun fi oju mi wo, ni kedere, mo wa ri pe, ę ko di ọro otitọ ati aşę Olugbala wa mu, pe "ki ẹnyin ki o fe ọmọnikeji nyin gẹgẹ bi ara nyin" nipa ọrọ ribiribi ati aşę totọ yi, ni ẹnyin le fi gbin eso rere silẹ fun awa ọmọ nyin lẹhin ọla. Bi ę ko ba şe eyi, ani fi ifẹ toto ati irẹpọ da awa ọmọ nyin pọ, ki ę to sun pẹlu awọn Baba nyin; emi Samuel Woli Kekere, ko bẹru lati so fun irufẹ Baba na (ibajẹ Ọlọla ni tabi alailọla, ibajẹ Onişegun Agbẹjọro ati Onişegun ẹmi) pe ẹbi na mbẹ lori irufe Baba na, ki o to tẹri gbaşọ ati lẹhin iku Baba oniwakiwa na; emi Samuel Woli Kekere si fẹ ki Baba na ti iru ero bẹ ba wa l'ọkan rẹ, ki o ranti ọrọ inu iwe mimọ ni "olukuluku ni yio ro ti ara rẹ ni iwaju idajọ," ati pe ki Baba na ki o tun mọ daju daju pe "gbogbo işẹ ti Olodumare yio mu wa si idajọ." Emi woli kekere si tun fẹ ran irufẹ Baba alaini ifẹ "ti o je pe ti ara rẹ nikan lomo na loti-owe ẹru to di Ọba lori oluwa rẹ." A ko sa mọ ibiti ori mba ęşę re, o sa mọ, iwọ Baba ti ati fi ifẹ dapọ mọ ẹlẹgbẹ rẹ fun atunşe ẹhin ọla, fun awa ọmọ nyin di ẹru ti o wọ ẹ l'ọrun, abi ti ipo rẹ ati ọla rẹ laiye yi, ko jẹ ki o le şe abi fi irufẹ ọna rere yi lelẹ di itiju ati ẹgan ati ọrọ isọkukọ, alufanşa ọrọ ti ko ni janu fun ọ; ti ọla rẹ ati ipo rẹ aini ifẹ ọmọ nikeji ẹni na di ayọkẹlẹ ti o nrin ẹ, kiri ninu Mọto lopopo ode Eko, emi Woli Kekere bẹ ọ tẹlẹ ki o şọna ki o ma fi Mọto na tẹ emi Woli Kekere mọ lẹ o.

Samuel Woli Kekere, ọmọ Afrika nwi, ọmọ Kekere ti oju rẹ si nwi "eniti o ba l'eti ọkàn lati fi gbo ko gbọ ni iwoyi ohun ti Woli Kekere nwi." Ẹ mọ daju pe, agbara ire Ilu nyin lẹhin ọla mbẹ lọwọ nyin papa ire fun awa ọmọ nyin lẹhin ọla wa ni ikawọ ifẹ ati ajọşe nyin. Ọbangiji Ọba ogo yio si ran nyin lọwọ.

Samuel Woli Kekere ko jade lati bu ẹnikẹni abi gbun ẹnikẹni, emi Woli Kekere jade lati "ke rara" kişe lati "dasi" lati fi "irekoja ati ęşę nyin han" kişe lati "da nyin l'ẹjọ" eyiti emi Woli Kekere ri li ẹlomiran nşe "ida ọmọnikeji eni l'ẹjọ" sugbọn a sẹhin wa a sẹhin lọ, idajọ kanna ti o da ẹnikeji rẹ, li on papa şubu yakata si, ti o si nfi ẹnu, imu ati ori yilẹ ninu rẹ, ẹ wo iwe Mathew ori 7, ęsę 1, 2.

SAMUEL—*Woli Kekere*

[ *Koi li pari* ]

---

## NOTICE.

IN THE MATTER OF THE ESTATE OF

LAWANI BAMGBADE LAYENI,

(Deccased.)

*Pursuant to the Statute 22 & 23 Victoria, Chap 35.*

NOTICE IS HEREBY GIVEN that all creditors and other persons having any debts, claims or demands upon or against the estate of LAWANI BAMGBADE LAYENI, late of No. 75, Broad Street, Lagos, Nigeria, who died on the 4th day of September 1921, intestate, and Letters of administration of whose personal property were granted by the Supreme Court of Nigeria to us the undersigned are hereby required to send in particulars of their debts claims or demands in writing to us at 4 Layeni Street, in Lagos, aforesaid on or before the 31st day of January 1924, after which day we will proceed to administer the estate and distribute the assets of the said deceased amongst the persons entitled thereto, having regard only to the claims and demands of which we shall then had notice and that we will not be liable for the assets of the said deceased or any part thereof so distributed to any person or persons of whose claim or demand we shall not then have had notice

And all persons indebted to the said estate are hereby required to make immediate settlement of their accounts.

Dated at Lagos, this 24th day of October, 1923

AKIN : ADESIGBIN,
IMORU LAYENI,
*Administrators.*

### SWORD OR PEN?

The Pen and the Sword a council held
At which old Time presided ;
And which should wear the Evergreen Crown
Was by him to be decided.
"The laurels I bring," the Sword began,
"Were won in a glorious cause ;
I have hurled from the throne the tyrant kings
Who invaded their peoples' laws.

The Pen replied, in a modest tone,
"See the good that I have done ;
I have taught mankind that Right is Might,
From the prince to the peasant's son.
I have saved full many a nation's blood
From being spilled in a useless strife.
And my laurels are Peace and Plenty
Which I spread on the field of Life."

Old Time his impartial balance held,
And their separate merits weighed ;
But soon to the modest Pen decreed
A crown that should never fade.
"Go, Sword !" Mid thy fading laurels rust,
For brief is the span I afford ;
And know that the Pen, the glorious Pen,
Shall through ages outlive the Sword."

— *James Simmonns.*

*From The Christan Life 10/6/22.*

---

### LEMỌMU LIGALI OLOHUN IYỌ. GBERE RẸ.........

Kosibotiri ni Jimọh ti awọn Musulumi ki lana ninu Mọṣalaṣi Jimọh ni opopo *Victoria*, nitori o jẹ Jimọh Ekinni ti a o kọkọ ki lẹhin igbati a ti fi Alufa Ligali Nọla jẹ Lemọmu Agba ni *Sunday* tokọja dipo Lemọmu Braimah ti kosi: bi omi ni en a nwọ, awọn Ọpa Ọba ati Olori Ọlọpa diẹ wa sibẹ lati tọju Alafia Ilu.

A gbọ pe lati arọ ana ni pupọ ninu awọn Jama Ilu ti wa ni Mọṣalasi na nigbati nwọn ngbọ finrinfinrin pe boya awọn kan le wa gba ọna-ẹburu fi obẹ ẹhin jẹ wọn ni 'ṣu: ṣugbọn titi nwọn fi ki Irun tan, lati agogo kan abọ ọsan ti Lemomu Ligali si fi ohun oyin ke Khutuba, pẹkẹ kan ko mi. Awọn ero oworan na lana ko niye.

---

### AIYELẸSỌ ỌLARINDE

Repairer of all kinds of Bicycles, Gramaphones Fitting and Sewing Machines.

*Workshop* :—20, Williams Street Lagos.

*Residence* :—135 Igbosere Road.

**Charges Moderate.**

## IROHIN ODE ONDO.

### AWỌN ẸGBẸ AKEWI

Ni ojọ ogun oṣu *October 1923* ni a da ẹgbẹ yi silẹ ni Ondo, a si yan awọn ẹni mẹta si ipo larin ẹgbẹ na. Bi a ti yan wọn niwọnyi :—

| | | |
|---|---|---|
| D. A. Akinkugbe | Esqr | *Chairman,* |
| J. S. Martins | ,, | *Secretary,* |
| M. D. Gboko | ,, | *Treasurer.* |

MEMBERS.

| | | | |
|---|---|---|---|
| D. A. Awoshika | Esqr. | S. R. Fadashẹ | Esqr. |
| R. A. Ayọdeji | ,, | C. Ọla. Awoshika | ,, |
| J. O. Awoshika | ,, | S. Iluyọmade | ,, |
| I. E. Colombus | ,, | S. C. Adefusi | ,, |
| J. F. Akinrele | ,, | D. K. Akinmurele. | ,, |

Iye awọn enia ti a darukọ yi ni o kọ da ẹgbẹ na silẹ. A si ro pe laipẹ omo ẹgbẹ na yio tubọ ma pọ si. Ki Oluwa jẹ ki a le ṣe pẹ o

### MILLER BROTHERS (of Liverpool) LTD.

Ọkan ninu awọn Oyinbo Oniṣowo yi de si arin ilu ni ojo kẹdọgbọn oṣu *October* lati wa ṣe eto fun oja tita ati rira larin wa, o si lo wo ile Ogbẹni Kadiri Ladapọ ti o wa ni Ododibo wo. A si ro pe laipẹ inẹ ni yio fi ṣe ile ọja tita ati rira.

Oyinbo yi si ti ri awọn Ijoye ilu ati Ọba Oshemọwe nipa rẹ.

### ỌNA IGBORO.

A ko le ṣe ki a ma tun sọ nipa Ona yi. O jẹ ohun abuku fun ilu papọ, pe *Motor* ko le koja ni igboro wa, a tun bẹ awọn alaṣe ilu lati ṣe atunṣe yi. Papa ni eyiti awọn Onişowo nde si arin wa yi.

---

## *IN MEMORIAM.*

Ni iranti Ologbe mi JOHNNY ALABA BANJIRO GEORGE to fi ilẹ ṣe aṣọ bora ni Ijọ kẹfa Oṣu *November 1922.*

Bo fẹ gba ohun ọwọ mi
Ohun to ṣe ọwọn fun mi
Ngo fi fun Ọ ṣe tirẹ ni
Ṣe ifẹ rẹ

ALABA o,
Odigbere Odi arinnako,
O doju ala o,
Odigbere o dọdọ Oluwa
O doju ala o!
A Aburo mi,
A o tun fayọ pade l'ọla-Ọlọla.

AGBOỌLA COKER.

## Preachers for To-morrow.

AWỌN ONIWASU ỌLA.

ROMAN CATHOLIC (HOLY CROSS)

Masses will be sung by Priests appointed.

Awọn Paddi ti a yan yi o ṣe Isin ni gbogbo ǝkoko wọnyi. ( MORNING )

Masses Isin Arọ.

0.30 7.30 8.30 9.30
7.30 8.30 9.30 10.30.

( EVENING.)

Masses ( Benediction ) Isin Ibukun.

4.45—5.30 6.45—7.30.

ST. MICHAEL'S ( Lafiaji.)

MORNING. 7 a.m — 8 a.m. 8.30 a.m.—9 30 a.m.
EVENING. 5.45—6 30 p.m.

ANGLICAN

| Time. | | Preacher. |
|---|---|---|
| 9 a.m. | Christ Church | The Vicar |
| 6.30 p.m. | do. | do. |
| 9 a.m. | St. Paul's (Breadfruit) | Ven. Archdeacon T. A. J. Ogunbiyi |
| 6.30 p.m. | do. | do. |
| 9 a.m. | St. John's ( Aroloya) | Rev. H. V. E. Johnson |
| 6.30 p.m. | do. | do. |
| 9 a.m. | St. Peter's (Alapako) | |
| 6.30p.m. | | |
| 9 a.m. | Holy Trinity (Ebute-Ero) | Rev. S. J. Gansallo |
| 6.30 p.m. | do. | do. |
| 9 a.m. | St. David's ( Jordan ) | Rev. J. A. Leigh |
| 6.30 p.m. | | do |

WESLEYAN

| | | |
|---|---|---|
| 10 30 a.m. | Tinubu | Rev. D. A. Bababunmi |
| 7 p.m. | do, | „ A. N. Cole |
| 10 30 a.m. | Ereko | „ E. K. Ajai-Ajagbe |
| 7 p.m. | do. | „ D. A. Bababunmi |
| 10.30 a.m. | Olowogbowo | „ S. A. Pearce |
| 7 p.m. | do. | „ E. E. Williams |
| 10.30 a.m. | Ọbun Eko | do. |
| 7 p.m. | do | Rev S. A. Pearce |

AFRICAN (COMMUNION)

| | | |
|---|---|---|
| 9 a m. | Jehovah Shalom | Rev. G. A. Oke |
| 7 p.m | do. | „ M. B. Newton |
| 9 a.m. | Erelu | „ J. F Ogunko |
| 7 p.m | do | Bro. P. D. G. |
| 9 a.m. | Bethel | „ A. Ọbadina |
| 6 30 p.m | | „ A Aboyade-Cole |
| 9 a.m. | Zion | „ B. A. en amin |
| 6.30 p m. | do. | Rev. N. J. D. Shomuji |
| 10.30 a m | African Methodist | Bro E. A. Amosu |
| 4.30 p.m. | | „ S. A. Fatolu |

FIRST BAPTIST CHURCH

| | |
|---|---|
| 10.30 a.m. | Bro. R. O. Macaulay |
| 6 30 p.m. | Rev. J. R. Williams |

9 a.m. Ararọmi ( Baptist ) Rev. E. C. Alabi
5 p.m. Bro. E. A. Ojo

EBENEZER (BAPTIST)

9 a.m.
6.30 p.m. Rev. E. C. Alabi

BROTHERHOOD

| | |
|---|---|
| 7.30 a.m. Ilupesi | Bro. S. A. Coleman Daniel |
| 7 p.m. | Prof : Adeoye Deniga |

St. STEPHEN'S (EPETEDO)

9 a.m. & 4 p.m. Rev. A. Adekọya

AHMADIA (ISLAM)

6 a.m. Fajir Service Y. P. O. Ṣodẹyinde
5 30 p.m. Open Air Service Imam K. R. Ajose ( Bamgboṣe Street )

COLONIAL CHURCH (ODAN)

8 a.m.—Holy Communion
6.45 p.m — Evensong and Sermon, Revd. H. A. Lewis

SALVATION ARMY.

10 a.m. Capt. A. A. da Costa
3.30 p.m. Children's ( HARVEST ) 7 p.m. Lieut-Colonel Geo : H. Souter

CHURCH OF GOD

10 a.m. 22 Ọdunlami Street, Breaking Bread
7.30 p.m Open Air Service at Campbell Square, Edwin Mathew & Wm. C. F. Terrell

---

IGBẸ L' OWO WÀ.

LAGOS—EKUKO.

Bi awọn oyinbo i'e-ôwò wọnyi ti gba Ọja *( Produce )* l' ọṣẹ yi ni eyi.

Ẹgbẹ Odo-Ọya ( Niger Co.)

G. B. Ollivant

Oyinbo Agbẹra ( Lagos Stores )

MacIver, African Association, John Holt, Miller Bros. Cooperative Wholesale Society Ltd., Jurgens Colonial Product.

£13—£14 fun *ton* kan.

EPO.

£24—£26 ni gbogbo awọn Ẹgbẹ oyinbo ti a daruko wọnyi gba *ton* kan.

COCOA.

£14—£19 fun *ton* kan bakanna.

KANO—COMPETITIVE PRICES

Ground Nut—£10 10 per ton

Skins 1/9 per lb, Hides 5d per lb

LAGOS STEVEDORING COMPANY.

ALL STEVEDORING WORK

undertaken at lowest possible prices anywhere in the Lagos area.

GOODS HANDLED CAREFULLY AND EXPEDITIOUSLY.

Estimates given for the handling of goods under any circumstances.

*PRICES ON APPLICATION.*

TO

**S. I. M. Johnson,**

9, Scale Square,
Phone 227 Lagos,
P.O. Box 498.

***Wool, Wool, Wool.***

***Silk, Silk, Silk.***

Wulu tabi Siliki lo nfẹ ra ọmọ iya mi? Lọ si Ṣabu Iya Labu, nibẹ ni iwọ yio ri ni orişipe, Wulu ati Siliki lo fi şişẹ şe—Kọbọ ẹru.

( Abulati mbẹ pẹlu bi tẹdi, ọmọ iya Siliki ni. )

18 & 137, Victoria Street.

ẸNIKEJI,

Aşọ Oke to yanju mbẹ lọdọ Iya Afin Saamọta Ikẹ Ọlọrun fun tita, ọpọku Ọyọku ni owo wọn, lọ bere ni 3 St. John Street, l'Eko, leti ile Johnson Agbẹjọro.

FOR SALE

One upright grand Iron-frame Piano, with beautiful tone. New condition—Owner going on leave, and will repurchase on his return six months.

For Terms, etc., apply to the EDITOR,

**JUST THINK OF THAT.**



Persons desirous of selling or acquiring Houses or Land in the Colony of Lagos should communicate with

E. SOYEMI ALDER

who for many years has specialised in this class of Property. Sales effected by Public Auction or Private Treaty. Valuation for Mortgage or Probate carefully prepared. Loans arranged. Commissions reasonable.

☞ Please note address:—E. SOYEMI ALDER. Auctioneer, Valuer, etc., Owode (opposite the Law Courts) Tinubu Square, Lagos.

**The Union Night School.**

FOUNDED JAN. 1923.

The School prepares candidates for Cambridge, Preceptors and Government Clerical Examinations and also teaches all Infant and Primary subjects, Yoruba inclusive.

The School opens on Mondays, Wednesdays, and Fridays in the Breadfruit School (Top floor) For further particulars apply to

*THE SECRETARY,*
Union Night School,
P.O. Box 121,
Lagos.

ILE IWE ALẸ.

A da Ile-iwe alẹ silẹ fun gbogbo ọmọ Ile-iwe ati oşişẹ pẹlupẹlu fun awọn ti o nfẹ lati şe idanwo fun işẹ Ọba ati *Cambridge*, a si nkọ iwe Yoruba nibẹ. A nşe Ile-iwe yi ni ọjọ *Monday, Wednesday* ati *Friday* ni agogo meje abọ alẹ ni Ile-iwe *Breadfruit* ( Loke. )

Cable Address :—
"Steinafrik" HAMBURG.

E. H. STEIN & Co.

HAMBURG, Neurwall 16/18, Hildebrandhaus.
*AFRICAN MERCHANTS.*

***ALL INDENTS EXECUTED.***
for
English and Continental Goods
and
PRODUCE
Sold on Best Terms.

**Produce to Europe covered by Floating Marine Insurance Policy.**
*P. O. Box No. 505.*

Agent in Lagos :—

**Mr. Karimu Kotun**

Broad Street, & Portonovo Market Store.

---

ẸGBE OYINBO ONISOWO
E. H. STEIN ARA HAMBURG.
NEUERWALL 16, 18, GERMANY.

Jẹ awọn onişowo ti ilẹ Enia Dudu, nwọn ma nranşẹ Ọja fun ẹnikẹni to ba fẹ, ibaşe Ọja ti ilu Gẹsi tabi ti awọn Ilu Oyinbo miran ti o wa lagbegbe *England* ati *Germany*.

Nwọn si nba enia ta Ọja bi Epo tabi Ekurọ ti a ba fi ranşẹ si wọn si ilu awọn Oyinbo (*Europe*) ni owo ti o jọ enia loju.

Ko si ewu kankan ni fi fi Ọja-kọja ranşẹ si wọn lati Eko tabi ilu miran ni *Nigeria*.

Ki ẹnikẹni to ba fẹ ba awọn Oyinbo yi şowo lọ ri tabi ki o kọwe si Aşoju wọn nibi Ọgbẹni Karimu Kọtun ti ita Ọba Dosunmu No. 3, tabi ni ibi-işẹ rẹ (*Office*) ni Opopo-nla (*Broad Street*) ati ni ibi-ifi Ọja pamọ si (*Porto-novo Market Store*) l'Eko.

Ẹnikẹni le kọwe ni ede Gẹsi, niti *German* tabi niti *French*.

Orukọ adugbo awọn Oyinbo onişowo yi ni ede *Wire* ni STEINAFRIK, Hamburg.

---

**CHANGE OF NAME.**

I, Moses Richard Affun, Sanitary Inspector Ondo, will be known as from the 1st of November, 1923, as MOSES RICHARD AFFUN ADEGBULU.

All documents bearing the former name prior to this date, of course remain valid.

**JACOB AJAYI,**
*General Woollen Trader,*
has on hand Woollens in endless varieties at 50, Dosunmu Street, Lagos.
***Prices to suit everybody.***
*Call now, fortune awaits you.*

---

OGUN YANMUYANMU ATI EŞINŞIN.
(*Fly Catcher.*)

Eşe ti o fi njẹ ki Yanmuyanmu ati Eşinşin ko arun ba ọ, nigbati ogun rẹ wa ni arọwọto rẹ. Ẹgbẹrun pere ni (3d.) Ẹdẹgbarun fun mejila (2/3d a dozen.)

A si ni ipari olorun amu irun dara daradara, o si ma njẹ ki irun sunmọ, o si njẹ ki o ma kọmọna bi jigin, ari malelu a pada ẹhin. (*Hair preparations.*)

Kọwe tabi bere l'ọdọ.

DIPO TUNDE & Co,
P.O. Box 335,
30, Victoria Road,
Lagos, Nigeria.

---

NOTICE.

When replying advertisers, please mention "Eko Akete"

---

AKIYESI.

Ti ẹ ba fẹ lọ si ọdọ awọn ti o polowo ọja ninu Iwe-irohin yi, ẹ jare ẹ sọ pe ninu Iwe-irohin Eko Akete ni ẹ ti ri ipolowo ọja na ka.

---

*Ibi ni ẹnyin ro si mi—Şugbọn Oluwa mọ si rere.*
ỌKANLAWỌN BALOGUN BROTHERS
Dealers in best quality of Produce viz :—Cocoa, Kernels, Palm Oil, Skins of any kind etc., etc., etc.
*Head Office* :—16, BANKOLE STREET, LAGOS.
*Branches at* :—Lagos, Agege, Agbado, Ifọ, Itori, Wasinmi, Owowo, Ibara, Lafenwa, Ibadan, Ileigbo, Iwo, Ikirun and Oshogbo.
*A trial order will be thankfully solicited.*

PRINTED AT "TIKA-TORE" PRINTING WORKS, 20, MARKET STREET, LAGOS, AND PUBLISHED BY ADEOYE DENIGA AT 24, WILLIAMS STREET, LAGOS, WRITER AND LECTURER.